# IROHIN IMỌLẸ

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No 1,485, MONDAY OCTOBER 18 1965 (2D)


## Ẹgbẹ Ọdọ Afẹnifẹre Igbomina Fẹ Ṣe Ipade

EKO:- Ninu irohin kan to de ile iṣẹ wa lati ọwọ Adele Akọwe ẹgbẹ ọdọ Afẹnifẹre ti ilẹ Igbomina ẹka Eko Ọgbẹni R. A. Abdul Salami ni o ti ṣe alaye pe ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kerinlelogun oṣu yi pe gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na ni ilẹ Igbomina yio ṣe aiyẹyẹ ipade kan ni deede agogo mẹsan abọ owurọ ni 109B Alakoro Marina, Eko.

Ọgbẹni R. A Abdul Salami tun ṣe alaye ninu irohin rẹ pe gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na ni iha Ila Orun Ilọrin eyiti iṣe Oke-Ọdẹ, Babanla, Oro Agor, Share ati Ọra ni yio peṣẹ sibi ipade ọjọ na.

Ọgbẹni Salami ti iṣe Adele Akọwe ẹgbẹ ọdọ Afẹnifẹre ti ilẹ Igbomina ẹka Eko tun ṣe alaye ninu irohin rẹ pe gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na ni awọn si nfẹ ki o wa sibi ipade na. O tun ṣe alaye pe awọn Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ilẹ Igbomina yio ba awọn ọmọ ẹgbẹ na sọrọ ni ọjọ na ati pe ọpọlọpọ ninu awọn enia pataki miran ninu ẹgbẹ Afẹnifẹre ni yio tun ba awọn ọmọ ẹgbẹ na sọrọ.

# ALHAJI ADEGBENRO FARAHAN NIWAJU ADAJỌ

IBADAN: Gbogbo ile o kunṣọṣọ ti ẹsẹ ko si gbeji fun ogunlọgọ Ọkẹ ainiye awọn enia l'Ọkunrin ati l'Obinrin ti nwọn wa si ile ẹjọ giga Ibadan ni jẹta Ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi nigbati awọn Ọlọpa mu Alhaji D. S. Adegbenro, Adele Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre, ati awọn enia mẹjọ miran pẹlu rẹ, Oloye J. O. Ọdẹbiyi, Oloye Shogbẹin, Oloye Joel Babatọla, Adisa Adeoye, Oloye Julius Adetola Ọjẹku, J. O. Awopeju, Oloye Mujeed Agbaje, Bọla Shadipe, ati Oloye Lanlẹhin wa siwaju Ọlọla Adeyinka Morgan, Olori gbogbo awọn Adajọ fun Ipinlẹ Iwọ Orun.



Alhaji D. S. Adegbenro
Adele Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

Ẹsun ti awọn Ọlọpa fi kan awọn enia na ni wipe, ẹgbẹ awọn, UPGA lo wọle ninu ibo ti o kọja lọ yi, nitorina awọn si ti yan "Ijọba Fidikẹ" ni Ipinlẹ na.

Awọn Ọlọpa tun sọ pẹlu wipe, iru Irohin na, eyiti o jade ni ọjọ ỌjọRu ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi le da nkan silẹ, tabi ki o fi ero buburu si ọkan awọn enia Ipinlẹ yi ati yika gbogbo Orilẹ ede Afrika.

Lẹhin ti nwọn ti ka ẹsẹ na si awọn enia na lọrun tan, ni Ọgbẹni Tajudeen Oki, eniti iṣe abanirojọ pataki fun Ijọba wa dide, ti o si ṣe alaye fun Ile ẹjọ wipe ẹsẹ ti awọn enia na ṣe jẹ eyiti ile ẹjọ ko gbọdọ gba iduro fun wọn.

O tun ṣe alaye pe iwa ti awọn enia na hu jẹ ipenija fun Ijọba Iwọ Orun lẹhin eyi ni Ọgbẹni Oki wa mu iwe irohin "PILOT,, ọjọ kẹtala oṣu yi jade ninu eyiti nwọn kọ siwaju iwe irohin na wipe.

"Ẹgbẹ UPGA ti yan Ijọba ni Ipinlẹ Iwọ-Orun,, o wa o adajọ lati fi oju eto ofin ati idajọ wo ọrọ na wo, ki o si tun ranti awọn rogbodiyan ti o nṣẹlẹ yika gbogbo ipinlẹ na

Ọgbẹni Oki tun sọ fun ile ẹjọ wipe Ijọba ti wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun, ki awọn enia na to tun sọ fun gbogbo enia gbọ wipe awọn lo moke ninu ibo ti awọn di awọn si ti yan Ijọba titun,

Ọgbẹni Oki, tun ṣe alaye siwaju ninu ọrọ rẹ wipe, yio ni ewu lọpọlọpọ bi ile ẹjọ ba le gba iduro fun awọn enia na, pe ki nwọn ma a lọ si ile wọn,

Ni ipari ọrọ rẹ Ọgbẹni Oki sọ wipe on mọ daju pe awọn enia jankanjankan ni awọn ti awọn nba ṣe ẹjọ yi, ki isi nṣe wipe awọn enia na le salo, nitori ọrọ yi, ṣugbọn bi enia ba fi oju ararẹ ri awọn ohuti nṣẹlẹ yika Ipinlẹ yi, ko si eniti o le di oju rẹ si awọn nkan na, ki o si ma woran.

Ṣugbọn ọrọ pesile, nigbati Oloye Ayọ Okusaga dide duro niwaju adajọ ti o si bẹrẹsi sọ fun ile ẹjọ na wipe gbogbo ohun ti Ọgbẹni Oki sọ ko ri bẹ rara.

Oloye Okusaga sọ fun ile ẹjọ wipe, ṣe nitoripe Iwe Irohin kan tẹ ọrọ kan jade, ni Ọgbẹni Oki ṣe fẹ ki awọn enia kan sẹwọn ni nitorina?

O tun ṣe alaye wipe ni ọjọ kokanla ni awọn dibo; ni ọjọ kejila ni Alhaji Adegbenro sọrọ ti o sọ, nigbati o si fi nsọrọ yi ko ti si Ijọba kankan ni Ipinlẹ na.

Lẹhin ti Adegbenro sọrọ rẹ yi tan, ni Gomina to pe Oloye Akintọla lati yan Minisita; ki o si ma a ṣe Ijọba lọ, lati igba a Alhaji Adegbenro ko si ti tun sọ ọrọ kankan.

Oloye Okusaga tun sọ fun Ile ẹjọ wipe, gbogbo awọn enia ti awọn Ọlọpa mu na, fi Alhaji Adegbenro, ni nwọn ti sọ wipe awọn ko mọ ọwọ awọn ko mọ ẹsẹ ninu ọrọ ti o delẹ yi papapa julọ, ninu ohunti o jade ninu Iwe Irohin na, bẹẹni awọn ko mọ nipa "Ijọba Fidikẹ" eyiti awọn Ọlọpa mu wọn si wa si Ile ẹjọ fun.

Ni ipari ọrọ rẹ, Oloye Ayọ Okusaga sọ pe, ko ti si enia kankan lori aga Alakoso Ijọba, bẹni Gomina ko ti yan ẹnikan rẹu ni asiko na lati ṣe ibura fun, lẹhin ibo, nitorina, Alhaji Adegbenro ko jẹbi fun gbogbo awọn nkan ti o ṣe.

Alhaji Adegbenro si tun ni aṣẹ labẹ ofin eto oṣelu lati le sọ Wo Oju Ewe Kẹfa



Ayo Ọkusaga

# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No 1,485, MONDAY OCTOBER 18 1965 (2D)


## Ẹgbẹ Ọdọ Afẹnifẹre Igbomina Fẹ Ṣe Ipade

EKO:- Ninu irohin kan to de ile iṣẹ wa lati ọwọ Adele Akọwe ẹgbẹ ọdọ Afẹnifẹre ti ilẹ Igbomina ẹka Eko Ọgbẹni R. A. Abdul Salam ni o ti ṣe alaye pe ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹrinlelogun oṣu yi pe gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na ni ilẹ Igbomina yio ṣe ayẹyẹ ipade kan ni deede agogo mẹsan abọ owurọ ni 109B Alakoro Marina, Eko.

Ọgbẹni R. A Abdul Salami tun ṣe alaye ninu irohin rẹ pe gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na ni iha Ila Orun Ilọrin eyiti iṣe Oke-Ọdẹ, Babanla, Oro Agor, Share ati Ọra ni yio pesẹ sibi ipade ọjọ na.

Ọgbẹni Salami ti iṣe Adele Akọwe ẹgbẹ ọdọ Afẹnifẹre ti ile Igbomina ẹka Eko tun ṣe alaye ninu irohin rẹ pe gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na ni awọn si afẹ ki o wa sibi ipade na, O tun ṣe alaye pe awọn Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ilẹ Igbomina yio ba awọn ọmọ ẹgbẹ na sọrọ ni ọjọ na ati pe ọpọlọpọ ninu awọn enia pataki miran ninu ẹgbẹ Afẹnifẹre ni yio tun ba awọn ọmọ ẹgbẹ na sọrọ.

# ALHAJI ADEGBENRO FARAHAN NIWAJU ADAJỌ

IBADAN: Gbo.bo ile o kunṣọṣọ ti ẹsẹ k s gbeji fun ogunlogọ Ọkẹaimọye awọn enia l'Ọkunrin ati l'Obinrin ti nwọn wa si ile ẹjọ giga Ibadan ni jẹta Ọjọ Abamẹta t iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi nigbati awọn Ọlọpa mu Alhaji D. S. Adegbenro, Adele Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre, ati awọn enia mẹjọ miran pẹlu rẹ, Oloye J. O. Ọdẹbiyi, Oloye Shogbẹin, Oloye Joel Babatọla, Adisa Adeoye, Oloye Julius Adeola Ọjẹku, J. O. Awopeju, Oloye Majeed Agbaje, Bọla Shadipe, ati Oloye Lanlẹhin wa siwaju Ọlọla Adeyinka Margan, Olori gbogbo awọn Adajọ fun Ipinlẹ Iwọ Orun.

Ẹsun ti awọn Ọlọpa fi kan awọn enia na ni wipe, ẹgbẹ awọn, UPGA lo wọle ninu ibo ti o kọja lọ yi, nitorina awọn si ti yan "Ijọba Fidikẹ" ni Ipinlẹ na.

Awọn Ọlọpa tun sọ pẹlu wipe, iru Irohin na, eyiti o jade ni ọjọ ỌjọRu ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi le da nkan silẹ, tabi ki o fi ero buburu si ọkan awọn enia Ipinlẹ yi ati yika gbogbo Orilẹ ede Afrika.

Lẹhinti nwọn ti ka ẹsẹ na si awọn enia na lọrun tan, ni Ọgbẹni Tajudeen Oki, eniti iṣe abanirojọ pataki fun Ijọba wa dide, ti o si ṣe alaye fun Ile ẹjọ wipe ẹsẹ ti awọn enia na ṣẹ jẹ eyiti ile ẹjọ ko gbọdọ gba iduro fun wọn.

O tun ṣe alaye pe iwa ti awọn enia hu jẹ ipenija fun Ijọba Iwọ Orun lẹhin eyi ni Ọgbẹni Oki wa mu iwe irohin "PILOT,, ọjọ kẹtala oṣu yi jade ninu eyiti nwọn kọ siwaju iwe irohin na wipe-

"Ẹgbẹ UPGA ti yan Ijọba ni Ipinlẹ Iwọ-Orun,, o wa o adajọ lati fi oju eto ofin ati idajọ wo ọrọ na wo, ki o si tun ranti awọn rogbodiyan ti o nṣẹlẹ yika gbogbo Ipinlẹ na.

Ọgbẹni Oki tun sọ fun ile ẹjọ wipe Ijọba ti wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun, ki awọn enia na to tun sọ fun gbogbo enia gbọ wipe awọn lo moke ninu ibo ti wọn di awọn si ti yan Ijọba



**Alhaji D. S. Adegbenro**
Adele Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

Ọgbẹni Oki, tun ṣe alaye siwaju ninu ọrọ rẹ wipe, yio ni ewu lọpọlọpọ bi ile ẹjọ ba le gba iduro fun awọn enia na, pe ki nwọn ma a lọ si ile wọn.

Ni ipari ọrọ rẹ Ọgbẹni Oki sọ wipe on mọ daju pe awọn enia jankanjankan ni awọn ti awọn nba ṣe ẹjọ yi, ki isi nṣe wipe awọn enia na le salọ, nitori ọrọ yi, ṣugbọn bi enia ba fi oju ararẹ ri awọn ohuti nṣẹlẹ yika Ipinlẹ yi, ko si eniti o le di oju rẹ si awọn nkan na, ki o si ma woran.

Ṣugbọn ọrọ pesiie, nigbati Oloye Ayọ Okusaga dide duro niwaju adajọ ti o si bẹrẹsi sọ fun ile ẹjọ na wipe gbogbo ohun ti Ọgbẹni Oki sọ ko ni bẹ rara.

Oloye Okusaga sọ fun ile ẹjọ wipe, ṣe nitoripe Iwe Irohin kan te ọrọ kan jade, ni Ọgbẹni Oki ṣe fẹ ki awọn enia kan sẹwọn ni nitorina?

O tun ṣe alaye wipe ni ọjọ 'okanla ni nwọn dibo; ni ojo kejila ni Alhaji Adegbenro sọrọ ti o sọ, nigbati o si fi nsọrọ yi ko ti si Ijọba kankan ni Ipinlẹ na.

Lẹhin ti Adegbenro sọ ọrọ yi tan, ni Gomina to pe Oloye Akintọla lati yan Minisita; ki o si ma a ṣe ijọba lọ, lati igba a Alhaji Adegbenro ko si ti tun sọ ọrọ kankan.

Oloye Okusaga tun sọ fun Ile ẹjọ wipe, gbogbo awọn enia ti awọn Ọlọpa mu na, ti Alhaji Adegbenro, ni nwọn ti sọ wipe awọn ko mọ ọwọ awọn ko mọ ẹsẹ ninu ọrọ ti o dele yi papa julọ, nipa ohunti o jade ninu Iwe Irohin na, bẹẹni awọn ko mọ nipa "Ijọba Fidikẹ" eyiti awọn Ọlọpa mu wọn si wa si Ile ẹjọ fun.

Ni ipari ọrọ rẹ, Oloye Ayọ Okusaga sọ pe, ko ti si enia kankan lori aga Alakoso Ijọba, bẹni Gomina ko ti yan enikan rẹ nu ni asiko na lati ṣe ibura fun, lẹhin ibo, nitorina, Alhaji Adegbenro ko jẹbi fun gbogbo awọn nkan ti o ṣe.

Alhaji Adegbenro si tun ni aṣẹ labẹ ofin eto iṣelu lati le sọ Wo Oju Ewe Kẹfa



Ayọ Ọkusaga

# KỌKỌRỌ AIYE KO SI LỌWỌ ẸNIKAN

YORUBA NI:— "Erin ki ifọn, ki ọmọ rẹ o tun fọn" Emi ri wipe eyi jẹ ọkan ninu aṣipa owe to mbẹ ninu Owe ilẹ Yoruba, Ki Erin fọn, ki ọmọ rẹ fọn pẹlu baba rẹ lo dara ati wipe, iyẹn lo gbe Ọla Erin ga, Ki owe yi jẹ ti ẹnyin Ọjogbọn Onkawe "Irohin Imọlẹ" Nitorina mo juba baba mi 'Ẹrukobodo," Ọmọ Olabuse Ẹri-Ogun; Aṣakaṣiriki: Baba Adenre'e d'ogun duro d'agbalagba Ẹnyin Onkawe "Irohin Imọlẹ mo juba nyin o!

## Lati Ọwọ Omo Ẹrukobodo

### A KIIRIDI OKUN

Ki nto ma bi ọrọ mi lọ, o to ki nsọ ni gbolohun kan fun ẹnyin onkawe wipe mo ti nlo to nkan bi ọdun mẹ iwla ninu irin ajo mi laiye ati wipe' mo tun jẹ ọkan ninu ọmọ ile ẹkọ awọn Ahamadiyya ti nwọn npe ni Fazl-i omar School l'Eko, nibiti mo ti ri oluko atata ti o nfi gbogbo ara kọ wa ni itan ilẹ awọn bayi, bi wa, ninu eyiti ngo ti mu ninu itan na, han ẹnyin onkawe "Irohin Imọlẹ" bayi:— Ọpọlọpọ ni ninu awa ẹda to mbẹ nile aiye, ti o nhuwa ṣegebi ẹniti o ti fi oju kan Ọlọrun, iru awọn eni ẹ ni o ma nhu wa bi eni wipe nwọn ti mọ ohun ti Ọlọrun le ṣe.

Ṣugbọn o daju gbangba wipe, nigbati ẹnikan ko ti le ridi okun, ti a ko ri ẹniti o le ridi Ọsa, nko lero wipe ẹda kan tun mbẹ nile aiye ti o le mọ ohun ti Ọlọrun le ṣe lọ'la.

### OBIRI-BIRI L'AIYE

Bi a ba nwo elomiran ninu awa ẹda enia, ao ma ni ero wipe ko si ohun kan ti o tun le pa ipo rẹ da l'aiye ati wipe, ao ma ṣe lọkan wipe, iru ẹni bẹ ti ri ọla rekọja ẹjọ, o ti ga rekọja wahala, ola rẹ ti pọ ju ẹni ti iponju tun le ba lọ ati wipe ao ma rẹ iru ẹni bẹ si wipe, ile aiye ti di tirẹ nikan.

Ṣugbọn, ao ti gbagbe ne, "Obiri-biri nile niye". Ni aiku ati ni alẹ ko ṣamodi' igbesi aiye rẹ a si pada yi biri, eni'i a ti ka kun Ọ'ọla, Onibo ati Alakoso ilu, a si yipada di ẹni'i aṣọ rẹ rẹn ju aṣọ Aporo lọ. Aiye to'o hun ua!

L'ọna keji, ẹlomiran a ma bẹ ninu ipo isẹ, ipò iya atip iponju rẹ yio ju ti Ekute ile Ọlọrun lọ, bi a ba nwo, ọkan wa yio ma sọ fun wa wipe, Njẹ, eleyi tun le nilari mọ lode aiye?

Ao mo ro origirisi ero burukuṣi, bi ẹni wipe awa ni Ọlọrun to da a sile aiye,



## ERUKOBODO

Ao ti gbagbe wipe, "Kọkọrọ aye kosi lọwọ ẹnikan afi wipe Ọlọrun lo nṣe ohun gbog'o koni tọjọ bẹni ko ni foṣu Ọlọrun a si yi ẹniti a ti fọju iṣẹ wọ di Ọlọla ati ẹni apesin ninu aiye rẹ.

### KOITASIKO

Gẹgẹbi anejuwe ati gẹgẹbi ohunti oluko wa ni'e ẹkọ fi ye wa kẹhin ki a to bẹrẹ isinmi ọdun tuntun ti a bọ (Ki Oluwa ko ṣe ọdun nani ọdun rere fun gbogbo wa) Oluko wa na fi nye wa wipe, Nigba laila okunrin kan nbẹ o bi ọmọ mẹta iṣẹ oko ni ọkunrinna ati awọn ọmọ rẹ mẹtẹta nṣe nwon a ma gbin agbado ati oriṣiriṣi ohun ti eni njẹ nigbati agbado bagbo nwon a ya won a si ko sori aba ninu oko igba gbogbo ni awọn ọmọ na ma ndi lo so'ko binwon ba roko tan nwon a si mu agbado wa sile fun onjẹ o jọ wọn.

Ọkun iyi yi ko bimọ miran mọ to ju awọn ọmọ mẹta yi lọ, sugbọn, o ni aja kan ti o sọ orukọ rẹ ni "KOITASIKO"

Ni ọjọ kan, awọn ọmọ rẹ mẹtẹta lọ soko, nigbati nwọn ṣiwọ ninu oko, nwọn lọ sinmi si abẹ aba agbado, ko pẹ pupọ ti nwọn ti de abẹ aba agbado na, ni o wo lu wọn mọlẹ, awọn mẹtẹta si ku soju kanna.

Nigbati o to asiko ti nwọn ni lati dele, ti baba won ko ri wọn, o dide, o nwa wọn lọ nigbati o de inu oko o rii wipe aba agbado ti pa won bi ibanujẹ ti pọ fun to o ro ọrọ rẹ, debi ki o pokuso, ṣugbọn iṣẹkẹṣẹ ni ero miran tun sọ si lọkan wipe, Bi o ba pokuso, ti o ba ku nitori eyi, on ko mọ ohun ti Ọlorun e ṣe fun en l'ola Nipa bẹ, o ṣaragiri o pada sile lati lọ pe awọn ara adugbo ti yio ba a tufọ fun iya awọn ọmọ na ati awọn ti yio pẹlu sin oku awọn ọmọ na.

Lẹhin ti nwọn tufọ fun iya awọn ọmọ na tan ati wipe, ti nwọn ti sinku wọn tan, ni Iya awọn omo na ku, o ku Ọkunrin yi nikan pẹlu aja rẹ, own kosi fun lati fi ra Ẹru, ti i lati fi yawọfa, ou nikan lo ni o ṣe iwọnba iṣẹ to le ṣe ninu oko rẹ.

### KE PE ẸLẸDA RẸ

Ni ọjọ kan, baba arugbo yi lọ s'oko, ilẹ ṣu on ati aja rẹ, bi o ti mbọ, o ba awọn enia kan ni abẹ iṣọ Ẹlẹmu, bi ọkan ninu awọn to nmẹmu labẹ isọ na ti ri, o Bẹrẹ si fi baba arugbo yi ṣe yẹyẹ wipe Kini ṣe ti baba arugbo ti ọmọ mẹtẹta to bi ti ku tun nlọ s'oko di arin ọganjọ bayi ka to de? Ẹnikeji ninu wọn ni Ẹ ko mọ ni, lalin ọgọnjọ ni od ṣiwo tirẹ Ẹnikẹta ni.- Kotilẹ si ohun to npa mi lẹrin ninu ọrọ baba na, bi ko ṣe Oruko aja rẹ ti o npe ni KOITASIKO o wa Orukọ ti yio sọ aja rẹ titi ko ri, o ni KOITASIKO Ẹniti o ti darugbo tan, ti o nku lọ yi tun nsọ orukọ aja ni KOTASIKO Asiko wo ni ko ti to, Irun dudu ti di funfun, nigbawo lo tun ku? Awọn ọmọ mẹtẹta to bi ti ku, kosowo fun lati jẹun mọ, o ni as ko ko tito, nigbawo lo tun ku?

Baba arugbo na ufeti ara tẹ gbogbo ohun ti nwọn ṣe sii. o dakẹ o kọja lọdọ wọn pẹlu aja rẹ, Nigbati o wọnu ile rẹ, o bẹrẹ si fọwọ gba ori rẹ pẹlu gbolohun bayi:—Iwọ Ori mi! Iwọ Ẹlẹda mi!! Ṣe engbọn bi Ọmọ araiye ti nfi mi ṣe yẹyẹ? Ẹlẹda mi dahun maṣa jẹki igbẹhin aiye mi o dara ki nto fi ile aiye silẹ.

### TẸNI TOKU LOTAN

Ko tọjo ko to oṣu ti baba arugbo na ti nke pe Ẹlẹda rẹ, ni Ọba to mbẹ ninu ilu na ku nigbati awọn afọbajẹ to mbẹ ninu ilu na difa lati mọ ẹniti yio jọba baba na ni Ifa mu nwon si fi jọba.

Nigbati baba gori itẹ Ọba, o ranṣẹ lọ pe awọn to fi nṣe yẹyẹ ni ọjọ kini, nigbati nwọn de ọdọ rẹ, o sọ fun wọn wipe Ẹ maṣe bẹru fun yẹyẹ mi ti ẹ ti nṣe, ohun ti mo fẹ ki ẹ ṣe fun mi ni wipe, ki ẹ lọ ba mi wa ẹniti tirẹ ba tan laiye wa.

Lẹsẹkẹsẹ, awọn ọkunrin na lọ mu were wa fun un. Nigbati Ọba ri were na, o sọ fun wọn wipe; Teleyi ko ti tan laiye, bi a ba wo san, o tun le ṣe ohun rere laiye. Lẹhin na nwọn tun lọ mu Adẹtẹ; Akuwarapa ati Onijakutẹ wa fun, gbolohun kan na ni Ọba sọ fun wọn wipe - Bi a ba wo awọn ti ẹ lọmu wa yi, nwọn tun le ṣe rere laiye.

WO OJU EWE KARUN

# Babalawo Kan W'ẹwọn Ọdun Meje

ONITSHA:— Ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kejila oṣu yi ni Adajọ agba ile ẹjọ giga ti Onitsha paṣẹ pe ki okunrin Babalawo kan lọ si ẹwọn ọdun meje lori ẹsun pe okunrin Babalawo na Anthony Ejikemi pa ọmọ ile ẹkọ na eyiti Adajọ agba ile ẹjọ giga na si paṣẹ pe ki o lọ si ẹwọn ọdun meje oniṣẹ aṣekara.

Ninu ẹsun ti awọn Ọlọpa to ba ọdaran Babalawo na nṣẹjọ tẹlẹ fi kan ni wọn ti ṣe alaye pe Anthony Ejikemi pa ọmọ ile ẹkọ giga kan ti o jẹ pe ọdun kẹta ni o nlo ni ile ẹkọ giga na.

Ṣugbọn nigbati ile ẹjọ giga na bẹrẹsi gbọ ẹjọ na ni ile ẹjọ na ba yi ẹsun ti wọn fi kan Babalawo to pa ọmọ ile ẹkọ na ti oruko rẹ njẹ Chizoba Emeka di pe aṣiṣe lo fi pa ọmọ ile ẹkọ na.

Ninu ọrọ Ọlọpa to nba ọdaran Babalawo na ṣẹjọ ni o ti ṣe alaye fun ile ẹjọ giga na pe nigbati ọkunrin Babalawo na fẹ ba ọmọ ile ẹkọ na ṣe ogun ni o ba ku lori ogun ti Babalawo na nlo fun ọmọ na ninu oṣu kẹwa ọdun to koja lo yi.

Ọlọpa na tun fi ye ile ẹjọ giga na pe ponun mẹfa (£6) ni odaran Babalawo na gba lowo omo ile eko na lati le ba ṣe ogun na eyiti o jẹ wi pe nipa ogun ti odaran na nlo fun omo na lo gba ku patapata.

Ninu idajo Adajọ agba ile ẹjọ giga na Ọgbẹni Hyclenth Kaine ṣe alaye pe o jẹ ohun ti o ya on lẹnu lati ri pe ogun babalawo ti ọdaran na lo fun omo ile ẹko na lo pa omo na.

Adajo na tun ṣe alaye pe yio jẹ ohun iyalẹnu ti awọn ba le yẹ igi mo odaran babalawo na lẹse lori ponun mẹfa (£6) ti o gba lati le ba omo ile ẹko na ṣe iṣẹ ibi ra eyiti o fi pa omobinrin na.

Adajo agba ile ẹjo giga na tun ṣe alaye siwaju ninu idajo rẹ pe on yio ri pe iya to to ti o si yẹ ni on yio fi jẹ Ejikemi lori ẹsun pe o nṣe Dokita ti ko ba eto ofin lo ati pe o si nfun won ni ogun ti ko to na rara ati pe odaran na si so ara rẹ di Dokita ẹke.

Adajo agba na Ọgbẹni Kaine si paṣẹ pe ki odaran na yara lo si ẹwọn odun meje oniṣẹ aṣekara lori ẹsun na.


## IWE KOṢEMNI NI EYI

IWE ITỌSẸ OHUN GBOGBO
NINU ODU MẸRINDINLOGUN

Iwe yi kun fun Asọtẹlẹ ati wipe, yio din ọ lowo "YẸMIWO" ku, nitoripe iwọ na yio le ma da ṣe AYẸWO ara rẹ.

"KOṢEMANI" ni iwe na, 2/6d pere ni a nta Postage 9d tete lọ ra tirẹ ko to tan.

FI OWO RANṢẸ SI -
ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8, Idumagbo Avenue,
LAGOS NIGERIA
(Leti Ọja Jankara L'Eko)


## YE IRAWỌ RE WO

AQUARIUS (Jan 22 - Feb 20) O dabi ẹnipe arẹ fẹ mu ọ loni, ṣe ni ki o ṣe suru ki o si ma wadi ọrọ daju ki o to gbamu, ki o si bori ti awọn iṣoro ti o ba wa ninu iṣẹ rẹ.

PISCES (Feb 21 - Mar 20) O ṣẹ ki o jẹ anfani ire to mbẹ fun ọ loni ki o si yanju gbogbo isoro ti o mbẹ fun ọ, ki o ma si ṣe fi ibinu da ẹjọ ni idakuda

ARIES (Mar 21 - April 20) ẹjẹ ọna ti o tọ ni o wa ma to ọ niṣo, ṣugbọn ki o ma lo ọgbọn ori rẹ, nipa ṣe gbi o ti ṣe nnawo ki o maṣe na inakuna.

TAURUS (April 21 - May 20) Iṣẹ rẹ ojojumọ su ọ, o si nda ọ lamu nitorina, o ni lati ṣe suru, nitoripe ki a ma ba enia gbejọ tabi ki a ma ba enia kan ṣiṣẹ papọ. ko nṣe ohun ti o rerun

GEMINI (May 21 - June) Ṣe eto gbogbo ohun ti iwọ yio ṣe loni ki o si fi ara mọ eto na, yio si yọri si rere.

CANCER (June 22 - July 22) Ọjọ itunu ni oni jẹ iwọ yio si ma ṣiṣẹ rẹ lọ geregere, maṣe jafara ki o ṣe leto, bi gbogbo nkan yio ti ma lọ.

LEO July 23 – Aug 22 Bi o ba ngero kan lati bi enia kan ṣe adehun papọ, otitọ inu ati ododo ni ki o sọ nibẹ nitoripe adehun ti ọo ṣe ki iṣe nṣen ti eni le dalẹ rẹ

VIRGO Aug 23 - Sept 23 Orişiriṣi ọna li o wa fun ọ lọna kini odabi pe arẹ fẹ mu ọ, ọna keji ọkan rẹ nfẹ ki ẹ jọ ṣadeh n nitoripe ọkan rẹ nda si meji.

LIBRA Sept 24 - Oct 23 Bi o ba le ma ba iṣẹ rẹ lọ iwọ yio fi ọpẹ fun Oluwa ti o fun ọ ni ọgọ ọ.

SCORPIO Oct 24 – Nov 22 Ire nbẹ pẹlu rẹ lọna gbogbo, ọrọ ti o ba ba gbogbo enia sọ yio ṣe si ọ lẹnu

SAGITARIUS Nov 23 - Dec 21 Pinkit ni ara rẹ lo ni ṣugbọn maṣe jẹki aṣeju ba ila rẹ jẹ, tie ti ọrọ rẹ yio jẹ

CAPRICORN Dec 22 - Jan 21 Ire nṣe fun ọ lọ ọna gbogbo awọn eniti o fẹ yio ma nifẹ rẹ siwaju


BERE IGBOGI ARỌN

# 'Vermizyn'




Ojulowo egbogi atamatase ti o daju fun iparun awon 'ARỌN' Buruku gbogbo lara enia papa tabi ni pataki ARỌN latọnlatọn tabi arọ kinisa ti o ma mu idiwọ wa fun obinrin lati loyun tabi ti o ma nba oyun na jẹ lara Obinrin.

Bẹ si ni egbogi yi dara fun gbogbo ẹniti aran agbẹ igba aiya, ọna ọfun, sisẹ lẹhin bi ake tabi aran oju pelu Meji iru tẹ egbogi aron yi kosi ni gbogbo ilẹ Naijiria iṣẹ rẹ si daju.

AKIYESI PATAKI

Ri daju wipe o ti re eekọno ọwọ ati ẹsẹ rẹ daradara ki oto lo egbogi aran yi gẹgẹbi awọn Jaman ti o ṣe ti jowo lilo rẹ Fun agbalagba nikọn ni o wa fun Bere orisirisi egbogi arọn fun ọmọde pẹlu wọn nbẹ fun tita ni ṣọbu Naijiria bere ni:-

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square Lagos
WATERLOO MEDICINE STORES
8. Palmchurch Street Lagos
ATI NI ṢỌBU
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN.

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI [illegible]

No. 1,485 MONDAY OCTOBER 18, 1965 (2D)


## Egbe Odo Ijo Onitebomi Ti Ebenezer Yan Oloye Tuntun

EKO:- Gbogbo ese ẹdọ ni o kun ṣọṣọ ni ile Ọlọrun ti o njẹ "Ebenezer Baptist Church" Eko ni ọjọ Aiku ti ṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu to koja lati yan awọn Oloye tuntun fun ọdun yi paapa ẹṣẹ awọn Oloye ti o ti wa tẹlẹ ri lo pe ṣoṣọ sibi ipade na ni kete ti nwọn pari isin owurọ ni ọjọ na.

Nwọn fi adura bẹrẹ ipade na. lẹhin adura kukuru awọn yan Ogbẹni Ọlaku le ( niti o wa ni Yunifasiti ti Ibadan) lati mojuto yiyan awọn Oloye titun na. O jẹ ayọ ati idunnu fun gbogbo awọn enia ni ọjọ na, eyiti awọn ọmọ ẹgbẹ na ko ṣe iru ipade bẹ ri i lati igbati nwọn ti da ẹgbẹ na silẹ.

Awọn oloye tuntun na ni Ọgbẹni Ọshọ gegebi alaga ti Ọgbẹni Jaiye si jẹ igbakeji alaga, akowe agba ni Ọgbẹni Adeleke igbakeji akowe ni Ọgbẹni Amiko ti iyaafin Ọshọ si jẹ Akapo, ọgbẹni Ọjẹaiyẹ ni akọwe owo ti ogbẹni Aguda ati omidau Sekete si jẹ a yẹ iwe owo wo, akowe itankalẹ ni ọgbẹni Adelakun, awọn meji ti kiṣe oloye ti nwon wa ninu awon Oloye na ni Ogbeni Adebimpe ati iyaafin Taiwo.

Cbara ti nwon pari yiyan awọn oloye na tan ni nwon ba fi adura pari ipade gegebi iwa awọn Ijo Onitebomi. Oye yio mori o, amin.

# AWỌN OBINRIN ỌLỌJA EKO KO FARAMỌ IJỌBA ẸGBẸ DẸMỌ

EKO:- Ni deede agogo mẹrin irọlẹ ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi ni gbogbo awọn Obinrin ọlọja Eko ṣe ipade kan ni arin ọja Ereko ti gbogbo awọn Obinrin ọlọja na si ṣe ipinnu wipe "gbogbo awa Obinrin ọlọja ati Onisowo Eko ko faramọ Ijọba Oloye Samuel Ladoke Akintola,,,



OLOYE S, L. AKINTỌLA
Olori Ẹgbẹ Dẹmọ

Ọkan ninu awọn agbọrọsọ Obinrin ọlọja na ṣe alaye fun oniwe Irohin wa wipe lati ojo ti awon enia ti gbo Irohin pe ẹgbẹ Dẹmo Oloye Akintola lo wole ni awon ko ti ri awon onibara awon ni oja mo, ti nwon ma wa nra oja ni owo awon,

Obinrin na ṣe alaye wipe, lati bi ojo mẹta sẹhin ti awon ti nlo si oja lati ma lo ta oja awon ni awon enia ko ti wa ba awon ra oja mo.

Obinrin na ni titi ti Ọsẹ ti awọn lo kọja lọ yi fi pari, ko si ẹnikan ti o ti wa ba awọn ra Ọja. Bi awọn ba de Ọja, ijoko ni gbogbo awọn yio wa lati owurọ titi di alẹ ti awọn yio si maa wo ara wọn l'ọja.

Lẹhin nti awọn ti ṣe akiyesi yi fun bi ọjọ mẹta ni awọn wa bẹrẹsi wadi lọdọ gbogbo awọn enia ti won ti wa nba awon ra Ọja tẹlẹri, Ohun ti nwon ri ti nwon ko fi fẹ wa ba awon ra Ọja mo ?

Awon enia na si so fun awon wipe, lati ojo ti awon ti gbo wipe, Gomina ipinlẹ Iwo Orun, Ọlọla Ọdẹlẹyẹ Fadahunsi pe oloye Akintola pe ki o tun maa ṣe Ijoba Ipinlẹ Iwo Orun ni inu awon ti bajẹ ti inu awon ko si dun,

Obinrin na tun ṣe alaye wipe, ohunti awon enia na nso ni wipe, lati nkan bi odun mẹta ti Oloye Akintola ti wa ni aye Alakoso Ijoba ni oja ko ti ta mo, ko si tun si owo l'ode fun awon Onisowo.

Ṣugbon awon nfi ara da gbogbo nkan na lati igba a wa awon si ni ireti wipe, nigbati Ọlorun ba mu asiko de ti awon yio ni anfani lati dibo yan ẹniti awon ba fẹ, awon yo dibo fun ẹniti o ba wu awon.

Ṣugbon nigbati asiko na si de ni ojo Aje ti iṣe ojo kokanla oṣu yi gbogbo awon enia Ipinlẹ Iwo Orun ni nwon ti ṣe ipinnu pe ẹgbẹ UPGA ni awon yio dibo fun.

Gbogbo awon enia Ipinlẹ na lati Omode titi de agbalagba ni awon ko dibo fun ẹgbẹ Dẹmo ẹgbẹ UPGA ni awon dibo fun awon si ni ireti pe, ki ẹgbẹ UPGA le bo si ori aga akoso Ijoba.

Ṣugbon fun iyalẹnu awon nigbati irohin na jade nwọn so wipe ẹgbẹ Dẹmo lo wole bẹẹni nwon ko dibo fun ẹgbẹ Dẹmo, bi Dẹmo ti ṣe wa wole yi jẹ kayefi ati nkan mimaran ati iyanu enia nitoripe awon ko dibo fun ẹgbẹ Dẹmo.

Nitori idi eyi ni ko jẹki inu awọn enia dun, o ije ko wu awọn lati jẹ, koda, ebi ko tilẹ pa awon de ibiti awọn yio gbe jẹun, Ohun ti awọn enia nro lọkan ni wipe, "Njẹ bayi ni awọn tun wa fun odidi ọdun marun miran si i?"

Nigbati ẹnikẹni ko ra ọja awọn Obinrin ọlọja Eko ni gbogbo wọn ba pe ara wọ jọ, ti nwọn ti ṣe ipinnu ninu ipade kan ti nwọn ṣe wipe, "Awọn ko faramọ Ijọba Oloye Akintọla''

Lẹhin eleyi ni awọn Obinrin Ọlọja na yan enia mẹta ninu wọn pe ki nwọn lọ fi ipinnu won han Alhaji Abubakar Tafawa Balewa, ninu ile rẹ ni Onikan l'Eko,

Ṣugbọn ni ibi ti awọn enia na de ibẹ, awọn ọlọpa ko jẹki nwọn wọle lati lọ ba Balewa sọrọ, Ọlopa na si so wipe bi nwon ba fẹ ri Balewa, tabi ti nwon ba fẹ ba soro ki nwon lo ko iwe wa, Balewa yio si so fun won, asiko ti o ba tẹ ki nwon wa ri on.

Awon Obinrin na ti so fun akowe won pe ki o ba awon kowe si Balewa, nwon yio si mu iwe na lo fun Balewa ninu ile rẹ ni Owuro yi ni Onikan.

Agbọrọsọ awọn Obinrin Ọloja Eko na tun ṣe alaye fun Oniwe Irohin wa wipe, gbogbo awon Ọloja Eko ni nwon ko ni lo si Ọja loni, nitoripe, bi awon ba lo si Ọja awon ki i ta ko si ni dara to, ki awon maa lo joko silẹ lasan ni Ọja laiṣe iṣẹ kan.

O tun so pẹlu wipe. titi Balewa yio fi gbo ẹbẹ awon yi, ni awon Obinrin Ọloja Eko ni ta Ọja. Awon enia na ni Ijọba ti yio tu awon lara, ni awon nfẹ, awọn ko fẹ Ijoba ti yio ko Okuta ba Ọja awon.

Lati Oju Ewe Kini

ohunti o sọ ti yi, pẹkẹ ko si gbodo mi.

Ni pari ọrọ rẹ, Oloye Okusaga rọ ilẹ ẹjọ pe ki nwọn gba idoro fun awọn enia na, ti nwọn yio ba tilẹ ba wọn ṣe ẹjọ ki nwọn kuro ni Ọgba ẹwọn, ki nwọn maa ti ile wọn lọ si Kọtu.


Printed & Published by Modupe Printing Press 16, Bamgboşe Street, Lagos. Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street Lagos. 18/10/65